Ìsɔrunjɔ Agbin Ɔ̀jɛ̀ wa àan yèé àà kpè lí
(KOOP PROƐ́LÌ BENƐ́Ɛ̀ Ɛ̀)

# ÌWÉ ÌLÀNÀ SOJAÀ



Ilé Ishɛ́ yèé ɛ́ɛ̀ shàtìlɛ́yìn fí Àròko àan lɛ́kpasɛ̀
sojáà gbíngbìn lí ojúlɛ̀ Gbòmìnà ɛ̀
(ProA- CVA soja)

## 1. ÌMÚDÍYE

Àròko yèé ɛ́ɛ̀ gbin sojáà an ɔ́ ɛ́ɛ̀ gbìn ú si lí ìtálɛ̀ ojúlé wan. Àan kàn an ɛ́ɛ̀ gba alágbàshe àan, shí àan kàn an kɛ́ɛ̀ sɛ̀ gbà. Bójí ilɛ̀ oko wan kò kpɔ̀ ɔ́, ɛ́ɛ̀ jí ìdájì ɛtáà, shí yèé kpɔ̀ yɔ ɔ́ ɛ́ɛ̀ jí ɛtáà mɛ́jɔ. Ìshòro yèé ɛ́ɛ̀ wà bá àròko àan ɔ́ nìí jí sojáà yèé àà gbìn ɔ́ kɛ́ɛ̀ fú gangan ɛ̀. Ó she ɔ́ sojáà yèé àà mú ɔ́ kɛ̀ɛ̀ tó fí ònìyàn an gbo ilé ishɛ́ an gbo kánná fí ɛgbɛ́ yèé ɛ́ɛ̀ mú sojáà fu se iwun òríshi oríshi àan ɛ̀. Yèé ilé ishɛ́ KOOP PROƐ́LÌ shàgbɛ́yɛ̀wò ìshùwàn sojáà yèé àròko àan ɛ́ɛ̀ mú lí oko ɛtáà òbú lí ìtálɛ̀ Gbòmìnà ɔ́, à rí ní àà mú sojáà kìlóò mɛdógúlélɔ́gɔrú mɛrú (515), shí ìshùwàn yèénì ɛ́ɛ yɔ́ɔ dí nùmí ɛ́ɛ sɛ̀ yɔ́ɔ gùlé lí kìlóò òbúlélógójìlélɔ́gɔrú mɛ́ta (341) lírè kàn an. Líbɛ̀ ɔ́, ilé ishɛ́ yèénì rí ní ìshòro oríshi oríshi àán wà bá àròko àan. Ìshòro àan ɔ́ nìí: ɑròko àan kɛ̀ɛ̀ gba ɛ̀kɔ́ rere lɛ́kpasɛ̀ ɔ̀jɛ̀ gbíngbìn, àròko àan kɛ̀ɛ̀ lo ɔgbán yèé ònìyàn an ɛ́ɛ̀ lò l'oní shí ɛ́ɛ̀ she shí àà mú ɔ̀jɛ̀ rere ɔ́, shí bójí àròko àan ɔ́ mú ɔ̀jɛ̀ wan dábɔ̀, ɔ̀jɛ̀ ɔ́ kpíkpɔ̀ ɛ́ɛ̀ bàjɛ́ lɔ́ an. Báni bójí à kɔ́ àròko yèé ɛ́ɛ̀ gbin sojáà an ɔ́ lí ɛ̀kɔ́, à ká wà mú ɔ̀jɛ̀ kpere yèé àà ti mú tètè ɛ̀. Bójí àà ti mú ɔ̀jɛ̀ kìlóò ɔgɔrú (100), à ká wà mú ɔ̀jɛ̀ kìlóò mɛdógúlelɔ́gɔrú (115). Ɛ kó rɛ́ she shí ɔ̀jɛ̀ yèé à mú ɔ́ kò kó tɔ́ wà bàjɛ́ bɛ́ɛ̀ ró. Ɛ kó sɛ̀ rɛ́ she shí owó yèé àròko yèé ɛ́ɛ̀ gbin sojáà an àà rí ɔ́, ɛ kó gùlé. Bójí àà ti jɛ èrè àkpò òbú (1000) à ká wà jɛ èrè kpɔ́wùn mɛrú ó dí dɔ́là kánná (120) ɛ̀.

## 2. IWUN YÈÉ SHE Ɔ́

Àá mú ètò ɛ̀kɔ́ yèyí jokó shí ká fu ran àròko yèé ɛ́ɛ̀ gbin sojáà an ɔ́ lɔ́wɔ́ shí ká ma yebá à láti wà she oko wan gbà shí ká wà mú ɔ̀jɛ̀ rere ɔ́ kánná yebá à láti wà lo iwun yèé wà lɔ́ an ɔ́ gbà ɛ̀.

Iwun oríshi oríshi yèé wà línú ɛ̀kɔ́ an ɔ́ nìí :

- ✓ Ká kɔ́ àròko àan lí yebá à láti she gbà shí ká wà mú ɔ̀jɛ̀ rere ɛ̀.
- ✓ Ká kɔ́ àròko àan lí iwun oríshi oríshi yèé ɛ kó she shí bójí à gbin sojáà ɛ kó wà kpɔ̀ gùlé ɛ̀.
- ✓ Ká kɔ́ àròko àan lí yebá à ká ti wà lo iwun yèé wà lɔ́ an ɔ́ gbà ɔ́ kánná ɔ̀jɛ̀ yèé à mú ɛ̀.
- ✓ Ká kɔ́ àròko àan lí yebá à ká ti wà ta ɔ̀jɛ̀ yèé à mú ɔ́ gbà ɛ̀.

## 3. ƆNI YÈÉ LÁTI GBA Ɛ̀KƆ́ YÈYÍ AN Ɔ́

Ìwé yèyí jí ti olùkɔ́ an gbo ɔ̀gán àròko àan gbo kánná àròko àan

## 4. ÀLÀYÉ LÍÌTÁ SOJÁÀ

Sojáà jí ɔ̀jɛ̀ kàn shí ɔma ɛ̀ ɛ́ɛ̀ shí méjì baní ɛ̀wà, ìwere, àyɔ̀sín, nùmí kolo ni. Bójí kò ga ɔ́ gíga ɛ́ɛ̀ tó santimɛ́trù ogú bɛ́ɛ̀, shí bójí ó ga rere ɔ́, gíga ɛ́ɛ̀ kɛ̀ɛ̀ kpere mɛ̀ɛ́trù òbú. Òkún sojáà kàn án wà shí àà yá so (àà so lí gbàràgboro ɔjɔ́ mɛdógúlélɔ́góta '75' lɔ lí ɔjɔ́ mɛrúlélɔ́gɔrú '105'), shí ɔ̀kàn án sɛ̀ wà shí a kɛ̀ɛ̀ yá so. Àan yèénì an ɛ́ɛ̀ she kpere ɔjɔ́ mɛrúlélɔ́gɔrú (105) ítánná ká so. Yebá ɔ̀jɛ̀ yèélèé an ɛ́ɛ̀ so gbà ɔ́, sojáà katún ɛ́ɛ so shí èso ɛ̀ ɛ́ɛ̀ gbé lí ìkpòkpo. Bójí èso ɔ́ tutù si shí kò gbó ná, ɛ́ɛ̀ wà lómi ewé, shí bójí ó gbó ɛ́ɛ̀ di omi erúrú nùmí ɛ́ɛ̀ rɛná. Shí bójí ó gbɛ, ɔma ɛ̀ ɛ́ɛ̀ ta dànu. Bójí èso ɔ́ kò gù ɔ́, gúgù ɛ̀ ɛ́ɛ̀ jí santimɛ́trù mɛ́ta, shí bójí ó gù kpíkɔ̀ ɛ́ɛ̀ jí santimétrù marɔ̀kàn, shí ɛ́ɛ̀ lí ɔma méjì nùmí ɔma mɛ́ta. Sojáà ɛ́ɛ̀ lí egùgù kpàtàkì kàn, shí egùgù kékeré kékeré an ɛ́ɛ̀ wéjá ɛ̀ si. Lí ɔrun egùgù kékeré kékeré an ɔ́, àà rí ìkókó kàn an, shí ìkókó yèénì an nìí ɛ́ɛ̀ sɛ̀ she shí sojáà ɔ́ ɛ́ɛ̀ fú ilɛ̀ ibi à gbìn ú si ɔ́ lí ajílɛ̀ ɛ̀. Ítán shí sojáà kó fú rere ɔ́, ó láti rí omi gbo ojórùn gbo. Lírè yèé omi láti wà ká u àan ɔ́ nìí: ìrè yèé à gbìn ú ɔ́, ìrè yèé ó kàn títɛná ɔ́ kánná ìrè yèé ó wà sema ɛ̀.




Ɔ̀kpìn sojáà an



## 5. LÍBI À KÁ YƆ GBIN SOJÁÀ GBÀ AN Ó KÁNNÁ YEBÁ À KÁ WÀ MÓJÚTÓ U RERE Ɛ̀

### 5.1 Ká wo òkún ilɛ̀ ɔ́ rere

Àà wò lá iwun kpíkpò ítán shí ká ní ilɛ̀ kàn bádé shí ká fu gbin sojáà. Kpàtàkì ɔ́, àà wò lá ilɛ̀ yèé à lí ɔ́, ojúlɛ̀ ɔ́, kánná yebá ayé ɔ́ ɛ́ɛ̀ gbé gbà lásìkò lásìkò líbɛ̀ ɛ̀.

- ✓ Òkún ilɛ̀ ɔ́: Àa yɔ́ɔ gbin sojáà lîìtá ilɛ̀ ibi yanrìn gbo amà gbo jìjɔ́ wà ɔ́ nùmí ilɛ̀ etídò nùmí ilɛ̀ amà. Ilɛ̀ ibi amà gbo yanrìn gbo jìjɔ́ wà ɔ́ nìí ɛ́ɛ̀ sàn yɔ fí sojáà ɛ̀. Iwun yèé she ɔ́, ilɛ̀ yèénì ɛ́ɛ̀ baní omi odé.
- ✓ Ojúlɛ̀ ɔ́: Ojúlɛ̀ ibi àà gbin sojáà ɔ́ láti jí ilɛ̀ kpɛ̀ɛ̀rɛ̀rɛ̀ nùmí ilɛ̀ yèé ɛ́ɛ̀ da omi odé ɛ̀.
- ✓ Ilɛ̀ kpàtàkì yèé àà fu gbin sojáà ɔ́ nìí jí ilɛ̀ yèé ɛ́ɛ̀ baní omi rere bójí òjò rɔ̀ ɛ̀. E máa wà gbin sojáà lîìtá ilɛ̀ yanrìn nùmí ilɛ̀ amà. E máa wà gbìn ú lílɛ̀ òkúta nùmí ilɛ̀ ìshɔgí nùmí lílɛ̀ kpɔtɔ. E máa wà gbin sojáà lîìtá ilɛ̀ ibi òkúta funfun yèé ɛ́ɛ̀ bù shùkɛ̀shùkɛ̀ shí àà kpè lí 'Calcaire' lí èdè frasé ɔ́ ɛ́ɛ̀ gbé ɛ̀. Ilɛ̀ ibi àà gbin sojáà ɔ́ sɛ̀ láti má si.



### 5.2 Ìmúra yèé àà kpàshɛ̀ she fí ilɛ̀ ɔ́

Bójí à ré oko ɔ́ shí òjò oshù ɔ̀hanwi kanná oshù òjò rɔ̀ kpa ú, à láti fu ɔkɔ́ fu ro ú nùmí lí lalá numí mashínì. À yɔ́ɔ ro ú nùmí àa sɛ̀ yɔ́ɔ tú u. Ebè oko sojáà láti ga kpere ti gbàdo gbo òwú gbo.
Àa yɔ́ɔ kó ìkùlé ɔ̀sìn an nùmí ìtákùdì fányán dà lí oko ɔ́ ítán shí ká ro ú. À ká wà yan tɔ́nù méjì fányán dà lí oko ɛtáà òbú.



### 5.3 Iwun yèé à gbìn lí oko ɔ́ wáa lɔ ɛ̀ (ɔ̀kàn lɛ́yìn ɔ̀kàn)

Bójí à gbin sojáà lîìtá ilɛ̀ kàn, ó sàn fí ɔ̀jɛ̀ òmírìn yèé àà wáa gbìn líbɛ̀ ɔ́ yèé ewé ɛ̀ kɛ̀ɛ̀ na yá jirà núwàn kó yá fú ɔ̀jɛ̀ lí ajílɛ̀ ɛ̀.
Àa yɔ́ɔ gbin sojáà líbi à gbin gbàdo nùmí àyɔ̀sín nùmí ɛ̀wà nùmí líbi à lɛ́ àjagún wáa lɔ ɛ̀. Àa rɛ́ yɔ gbin ú líbi à jɔ̀ɔ́ shí a kò she fí ɔdún méjì nùmí ɔdún mɛ́ta ɛ̀.
E máa gbin sojáà lí ìtálɛ̀ òbú ɔ́ fí ɔdún méjì. Yèénì ɔ́, è she yìn fí arùn kàn an shí koríko kú koríko kàn an kò kó sɛ̀ wù lóko ín.

***Bójí ilɛ̀ kàn jí ilɛ̀ yanrìn : ó she kpàkàtì shí ká fú ibɛ̀ lí oríshi ajílɛ̀ kàn an shí ká fu fú ilɛ̀ ɔ́ lí àmí rere. Iwun yèé she ɔ́, ilɛ̀ ɔ́ kɛ̀ɛ̀ lí àmí rere. Ó yɛ shí ká wà fán ilɛ̀ ibɛ̀ lómi rere torí omi kó wà ká u nùmí ká sɛ̀ wà kó koríko gbígbɛ fu bo ilɛ̀ ɔ́ lɔ shí kó ma wà sàtayin.***

## 6. ÒJÈ GBÍNGBÌN



### 6.1 Ká wo oríshi irúgbìn yèé sàn rere ɔ́ shí ká gbìn

Ká lo irúgbìn ìdì ishɛ́ yèé ɛ́ɛ̀ shishɛ́ lɛ́kpasɛ̀ sojáà an ɔ́ nùmí irúgbìn yèé à rí ní ó sàn rere shí bójí à gbìn ú ɛ kó yɔ wù ɔ́ (ká ma wà gbin irúgbìn yèé à ti kìn si lí ènù shí ó ti kpere ɔdún òbú ɔ́, torí bójí à gbìn ú kɛ̀ɛ̀ wù rere).

Bójí irúgbìn tuntun kò sí shí ó jí irúgbìn yèé à ti kìn si lí ènù ɔ́ dódó ján wà ni ɔ́, ó yɛ shí ká sha irúgbìn yèé sàn yɔ àan ɔ́, shí ká gbìn ú wòrí shí ká mà dájú dájú ní ɛ kó wù.

Irúgbìn òkún yèé àà gbìn lí Benɛ́ɛ̀ an ɔ́ nìí: TGX (TGX 1910 14F) nùmí 1844 18E ti IITA) nùmí irúgbìn yèé àà kpè lí Jupiter ɔ́.

Irúgbìn òkún òmírìn yèé à ká yɔ gbìn an ɔ́ nìí:

- IRSA 2972,
- IRSA 44A/73
- TC x 536-02D

Irúgbìn yèé àà kpè lí TGX 1910 14F ɔ́ nìí ɛ́ɛ̀ so yɔ lí ìtálɛ̀ Benɛ́ɛ̀ líshàyí ɛ̀.



### 6.2 Ìrè yèé àà gbin sojáà ɔ́

À láti wà wò lá àsìkò yèé òkún sojáà yèé à wà wò ká gbìn ɔ́ ɛ́ɛ̀ she ɔ́ ítánná ká gbìn ú, torí àsìkò yèé à ká mú ɔ̀jɛ̀ ɔ́ kó wà bádé má àsìkò yèé ɔ̀rùn ɛ́ɛ̀ kàn yínyán ɛ̀.

Lí Benɛ́ɛ̀ ɔ́, àsìkò yèé àà gbin sojáà ɔ́ nìí:

Lérè Òku ɔ́: à ká wà gbìn ú lí kàlàjì ɔ̀sɛ̀ méjì àkpàshɛ̀ ti oshù Òjò ɔ́ tító lɔ lí ìkparí oshù Ishu ɔ́ bójí ó kpín kpíkpɔ̀.

Lérè Ɔ̀sa ɔ́: à ká wà gbìn ú lí kàlàjì ɔ̀sɛ̀ méjì ìkɛ́nyìn ti oshù Òjò.

### 6.3 Yebá sojáà yèé à wà gbìn ɔ́ ɛ kó wà wɔlɛ̀ gbà ɔ́ kánná ìshùwàn yèé à ká wà mú si lí kòtò ɛ̀

Bójí òjò yɔ́ɔ rɔ̀ tó ìshɛ́jú ogú shí ilɛ̀ ɔ́ tutù rere ni ká wà gbin sojáà lɔ́wɔ́ nùmí ká wà gbìn ú ùungbo mashínì gbo, shí kó wà wɔlɛ̀ tó santimɛ́trù mɛ́ta lɔ lí santimɛ́trù mɛrú. Bójí à ri sojáà lílɛ̀ kpímkpím kɛ̀ɛ̀ wù. Bójí sojáà ɔ́ kò wù rere ni ká wà yá rɔ́ u si línì ó kpín kpóó ɔ̀sɛ̀ òbú bójí ó wù dábɔ̀. À ká sɛ̀ wà rí sojáà kìlóò ɔgbàn lɔ lí kìlóò mɛrúlélɔ́gbàn ítánná kó wà tó gbin oko ɛtáà òbú.

### 6.4 Ìshùwàn ɔ̀jɛ̀ yèé à ká wà mú si lí kòtò ɔ́

Ká wà mú irúgbìn mɛrú si lí kòtò ɔ́ bójí à wà gbìn ú, shí bójí ó wù dábɔ̀ ni ká wà wáa tu ú bɔ̀, shí kó wà bɔ ɔ̀kpìn méjì nùmí ɔ̀kpìn mɛ́ta gɛ́gɛ́bá à ti jìnà lá ara wan gbà ɛ̀.

Yebá sojáà ɔ́ ɛ kó jìnà lá ara wan gbà lóko ɔ́ shí kó sàn ɔ́ níí:

• Lí oko kpatɛrɛ́ ɔ́, à ká wà gbin sojáà ɔ́, shí ɔ̀kpìn wan ɛ kó wà jìnà lá ara wan fí santimɛ́trù mɛdógú shí kàlàjì ɛkpa àan ɔ́ ɛ kó wà jí santimɛ́trù ogójì lá ara wan.

• Lí oko kpatɛrɛ́ ɔ́, à ká wà gbin sojáà ɔ́, shí ɔ̀kpìn wan ɛ kó wà jìnà lá ara wan fí santimɛ́trù ogú shí kàlàjì ɛkpa àan ɔ́ ɛ kó wà jí santimɛ́trù ogójì lá ara wan.

• Lí oko kpatɛrɛ́ ɔ́, à ká wà gbin sojáà ɔ́, shí ɔ̀kpìn wan ɛ kó wà jìnà lá ara wan fí santimɛ́trù ogú shí kàlàjì ɛkpa àan ɔ́ ɛ kó wà jí santimɛ́trù maálélógójì lá ara wan.

• Lí oko ebè gúgù yèé à ro si ɔ́, à ká wà gbin sojáà ɔ́, shí ɔ̀kpìn wan ɛ kó wà jìnà lá ara wan fí santimɛ́trù mɛdógú shí kàlàjì ɛkpa àan ɔ́ ɛ kó wà jí santimɛ́trù ɔgɔ́rin lá ara wan.

## 6.5 Inokulɔ́m̀

Fí irúgbìn kìlóò mɛdógú ɔ́, à láti rí inokulɔ́m̀ gàrám̀ ɔgɔrú lí ìbòjò kàn ùungbo súkèrè ɛyɔ mɛrúlélógú gbo kánná omi ìdámírin àdùgbá.







## 6.6 Sojáà tútu bɔ̀

À ká wà tu sojáà yèé kò gbilé nùmí sojáà yèé kò lí ìtɛ̀lɛ̀ rere àan ɔ́ kóò fí yèélèé an. Yèénì ɔ́, à ká wà jɔ̀ɔ́ sojáà ɔ́ ɔ̀kpìn méjì nùmí ɔ̀kpìn mɛ́ta bɔ̀. Bójí sojáà ɔ́ wù shí ó she ɔjɔ́ maá nùmí ɔjɔ́ mɛdógú níí à ká wà tu ú bɔ̀ ɛ̀.



***Ítán shí ká yɔ lí ìkara ní irúgbìn kàn sàn rere shí bójí à gbìn ú ɛ kó yɔ wù ɔ́, à láti kpàshɛ̀ yan irúgbìn ɔ́ odé si lí ǹkàn shí ká dán u wòrí lí ìdikàn fí ɔ̀sɛ̀méjì ítán shí àsìkò ɔ̀jɛ̀ ɔ́ gbíngbìn kó tó. Bójí irúgbìn maálélɔ́gɔ́rin ɛ́ɛ̀ wù línú ɔgɔrú, báni irúgbìn ɔ́ sàn rere nì. Àmá bójí irúgbìn yèé ɛ́ɛ̀ wù ɔ́ kɛ̀ɛ̀ tó ɔgɔ́ta línú ɔgɔrú, ɛ kó jí irúgbìn ɔ́ kò sàn, shí à sɛ̀ láti wo òmírìn fu rɔ́kpò ɛ̀ nùmí à ká wà mú kpíkpɔ̀ si lí kòtò ɔ́ bójí à wà gbìn ú. Bójí à wà wò shí ɔ̀jɛ̀ ɔ́ kó wù rere, shí kó rɛ́ lákún rere ɔ́, àa yɔ́ɔ rɛ ú lí ewé ítánná ká gbìn ú.***

# 7. À KÁ WÀ MÓJÚTÓ OKO ÀAN

## 7.1 Ká wà kpa koríko àan kóò lí oko

Ewé yèé ɛ́ɛ̀ kpa koríko àan ɔ́: Ká wà lo ìshùwàn ewé yèé bádé shí ɛ kó kpa koríko kóò lí oko sojáà an ɔ́. À ká wà lo ewé ɔ́ òbú lɔ lí mɛ́ta bɛ́ɛ̀ fí oko ɛtáà òbú. Ká wà fán ewé si lí oko ɔ́ lɔ́jɔ́ yèé à gbin ɔ̀jɛ̀ ɔ́ nùmí bójí ó kpín kpíkpɔ̀ ni, kó wà jí lɔ́jɔkéjì ɛ̀.

Oko ɔ́ shíshá: Bójí à ro oko sojáà rere, shí à shá u gbòbú ó ti tó nùmí àa sɛ̀ rɛ́ lo ewé yèé ɛ́ɛ̀ kpa koríko bójí ɔ̀jɛ̀ na ti wù si línì ɔ́ bójí ó wu ni.





## 7.2 Ká wà fú ilɛ̀ lí àmí

***Yebá à ká she gbà shí ɔ̀jɛ̀ ɔ́ kó wà fú rere, shí bójí à gbin ɛtáà òbú ni ká wà rí tɔ́nù méjì àbùbɔ̀ ɔ́ níí: Kùtùkùtù ɔ̀jɛ̀ ɔ́ kánná ìkùlé ɛran kìlóò ɔgɔrú mɛrú (500) kánná ajílɛ̀ NPKSBZn kìlóò maálélógóji (50) (13-17–17–6–0,5-1,5) kánná ajílɛ̀ K2SO4 kìlóò maálélógóji (50) kánná inokulɔ́m̀***

Bójí à gbin ɔ̀jɛ̀ ɔ́ shí ó she ɔ̀sɛ̀ méjì nùmí ó she ɔ̀sɛ̀ mɛ́ta níí à ká wà fú u lí ajílɛ̀ ti NPKSBZn kìlóò maálélógóji (50) ɛ̀. Shí bójí à gbin ɔ̀jɛ̀ ɔ́ shí ó she ɔjɔ́ mɛrúlélógóji (45) ítánná kó tɛná à ká wà fú u lí ajílɛ̀ ti K2SO4 kìlóò maálélógóji (50). Bójí a kò yá gbin ɔ̀jɛ̀ ɔ́ shí à mú àa yɔ́ɔ fú u lí ajílɛ̀ méjì an ɔ́ lí òbú.

## 7.3 Ɔ̀jɛ̀ ɔ́ kó yɔ gbé lí akpáni

Bójì kòkòrò án kan ɔ̀jɛ̀ ɔ́ bíbàbàjɛ́ ni, ká fán u léwé ìshùwàn yèé ó yɛ ɛ̀.
Arùn yèé ɛ kó yɔ wɔ̀ lí oko sojáà an ɔ́ níí: ewé sojáà gbo egi ɛ̀ gbo kánná egùgù ɛ̀ ɛ́ɛ̀ gbɛ hàà, shí ɛ́ɛ̀ lí omi tóm̀ tom tóm̀ lára, shí ɛ́ɛ̀ rɛ́ rɛná.
Bójí a kò wà wò shí arùn unhún bɛ́ɛ̀ kó wɔ̀si lí oko sojáà ni ó yɛ shí ká wà wo irúgbìn rere yèé à ti shishɛ́ lá shí à kpadí si shí à wà wò ká gbìn ɔ́ nùmí ká wo ewé yèé àà kpè lí Tiorálì ɔ́ gàrám̀ mɛrúlélógú fí irúgbìn kìlóò maá ítánná ká gbìn ú.

***Àa yɔ́ɔ shá oko ɔ́ ítánná ká gbin sojáà ɔ́, nùmí àa fán ewé si línì. Shi bójí à sɛ̀ gbin sojáà ɔ́ dábɔ̀ shí ó she ɔ̀sɛ̀ mɛ́ta ni ká lu kòtò shí ká fu fú u lí ajílɛ̀ yèé àà kpè lí NPK ɛ̀***

# 8.YEBÁ ÀÀ MÚ Ɔ̀JƐ̀ SOJÁÀ GBÀ Ɔ́ KÁNNÁ YEBÁ ÀÀ KPADÍ Ɛ̀ GBÀ Ɛ̀

## 8.1 Ɔ̀jɛ̀ ɔ́ múmú

Àà kan sojáà múmú bójí à rí fɔ̀ní línú ewé mɛrú ɔ́, mírin ti dà lí omi atalɛ̀, shí ewé ɛ sɛ̀ ti kàn gbígbàn shí èso ɛ̀ ti dà baní omi ilɛ̀ ni. Bójí ó yɔ dà bɛ́ɛ̀, àà shɛ́ egi sojáà ɔ́ lí ɔ̀kpìn ɛ̀ má ilɛ̀ rere torí egùgù ɔ́ kó fú ilɛ̀ ɔ́ lí ajílɛ̀. Ó sàn shí bójí à ká shɛ́ sojáà ni kó wà jí lí ǹkàn agogo méje lɔ lí agogo maá àarɔ̀ nùmí lí ǹkàn agogo mɛrú lɔ lí agogo méje alɛ́. Yèénì ɔ́, ɔma sojáà ɔ́ kò kó gbàn dànu bójí à wà shɛ́ u. Bójí à shɛ́ u tán, àà jɔ̀ɔ́ ɛ̀ si lójórùn líbi gbɛ ɔ́ nùmí lííta àtì gbígborò fí ɔjɔ́ maá bɛ́ɛ̀ torí kó gbɛ rere ítán shí ká gú u.



## 8.2 Sojáà sísá _ sojáà gúgú _ sojáà shíshábɛ́

### 8.2.1 Sojáà sísá

Bójí à shɛ́ sojáà, àà sá u lójórùn líbi gbɛ ɔ́ nùmí líìtá àtì gbígborò fí ɔjɔ́ maá bɛ́ɛ̀ torí kó gbɛ rere ítán shí ká gú u.

### 8.2.2 Sojáà gúgú

Sojáà gúgú ɔ́ níí jí ká yan ɔma ɛ̀ kóò lí ìkpòkpo ɛ̀ bójí à shɛ́ u dábɔ̀ ɛ̀. Àà kó u si lí ìdì lí ìdì líìtá àtì gbígborò nùmí líbi àà gú ɔ̀jɛ̀ shí à ti tɔ́she si ɛ̀. Shí lɛ́yìn bɛ́ɛ̀ ɔ́, àà fu ɔ̀kpá fu gú u.



### 8.2.3 Sojáà shíshábɛ́

Bójí à shábɛ́ sojáà ɔ́, kùtùkútù ɛ̀ yèé à gú ùungbo ɔma ɔ́ gbo ɔ́ ɛ́ɛ̀ wáa lɔ. Bójí à shábɛ́ ɛ̀ dábɔ̀, àà da ɔma sojáà ɔ́ dà lí àtì yèé à ti tɔ́she si ɔ́ ítán shí ká tà ú. Ɔma sojáà ɔ́ yèé àà gbìn ɔ́, àà kó yɛ̀ dà lí kpóúndoró, shí àà sé ɔrun ɛ̀ rere shí àà mú kpadí si lí ìkòùnkò lí ìdòdò líbi kɛ̀ɛ̀ gbóná kpíkpɔ̀ shí kɛ̀ɛ̀ sɛ̀ rɛ́ tutù kpíkpɔ̀ ɛ̀

.



***Bójí sojáà ɔ́ gbó tán, a kò láti dóro kpere ɔjɔ́ maá ítán shí ká shɛ́ u. E máa wà tu sojáà ɔ́,àmá e wà mú kpasha nùmí ɔkɔ́ shí e wà fu rɛ́ u málɛ̀, shí kó wà bɔ ɔ̀kpìn ɔ́ kánná egùgù***

### 8.3 Sojáà kpíkpadí

Àa yɔ́ɔ kpadí ɔma sojáà si lí àtì kpàkpàwó shí ká kó u si líìtá tèùnguè yèé à tɛ́ si lí inulé ìkpadí ɔ̀jɛ̀ líbi ayè wà rere ɛ̀.

Àa rɛ́ yɔ kpadí ɔma sojáà si lí àká nùmí lí àmù gɛ́gɛ́bá àà kin ɔ̀jɛ̀ gbà lí tuwa líbibí ɔ́ líbi gbɛ shí kɛ̀ɛ sɛ̀ gbóná kpíkpɔ̀ ɛ̀.



**Ilé Ishɛ́ yèé ɛ́ɛ̀ shàtìlɛ́yìn fí Àròko àan lɛ́kpasɛ̀ Sojáà gbíngbìn lí ojúlɛ̀ Gbòmìnà ɛ̀ (ProA-CVA sojáà)**

**Ìsɔrunjɔ Agbin Ɔ̀jɛ̀ wa àan yèé àà kpè lí**

**(KOOP PROƐ́LÌ BENƐ́Ɛ̀ Ɛ̀)**

''SCOOPS'' ɔ́ wà lí ojúlɛ̀ KÚTƆ́NU; lí ògbo ɛ̀kɛ́jɔ ; lí Ȧgbègbè Wɔ̀lɔ̀gɛ̀dɛ̀ ; Ilé DȮSÚ R. Elisabɛ́tì ; Ilɛ̀ : 442 ; 03 BP 0218 Jerikóò ; Okù ìkpè : 00 229 97448162 / 97046160 / 95285566 ;

Okù ikɔ̀: cooproel.benin@yahoo.fr.

Ce support a été réalisé dans le cadre du Projet d'Appui à la Chaîne de Valeur Agricole pour la Promotion de la Filière soja dans la commune de Glazoué (ProA-CVA Soja). Ce projet est mené par le Coopérative de Production et d'Exploitation Locale du Bénin Coop PROEL Benin

## *Remerciements :*

*Nos remerciements pour la réalisation de ce guide vont à l'endroit de :*

- *Toute l'équipe technique et opérationnel du projet*
- *Mr EMINAPKO, Secrétaire Général de la coop PROEL*
- *Mr Jonas HONGBEDJI, Chef projet*
- *Mr Farel CHABI formateur, Consultant à l'illustration et graphisme,*
- *Mr Doresse CHABI AKIN, formateur,*
- *Mme Edith ALLAGBE, formatrice.*